# ZIK GBAYI, O GB'EYE








Aworan oke yi ni ti igbati ogunlogo awon enia wa pade Gomina agba Naijiria ni Ilesha ni ojo Isegun ti ise ogbon ojo osu kerin odun yi, nwon si nyombo re pe, Z-e-e-k.! Z-e-e-k!! opolopo won ni o gbe patako oroirisi ti nwon ko akole ti o ka bayi pe, "Kuabo Zik, Are Naijiria, Ola Oluwa yio ran o lowo." Omiran ka bay ipe, "Omo Ilesha lokunrin l'obinrin ki Zik kuabo."
Ninu aworan kanna yi ni Iyaafin M. O. Aluko fi ododo se Gomina na loso ni oruko gbogbo awon omobinrin Ilesha.

Aworan otun yi ni igbati Gomina agba, Oba Alaiyeluwa Biladu keta, Owa Ilesha ati Gomina Ipinle Iwo Orun pelu ogunlogo enia jijo ya foto papo. Awon obinrin Ilesha ko dawo ilu lilu ati ijo jijo ni gbogbo igbati Dokita Azikiwe fo ni Ilesha.

Aworan egbe osi yi ni ti omobirin orekelewa kan ti o gbe namera ko lorun arimalelo awo pada sehin ni fun awon okunrin ti o ba pe daada. Erin ko jeki oko o naa tile ni obirin na, ehin enu ti o funfun bi yinyin tile nda okunrin lorun ganiyafiji ni aworan re, ewo o funrara yin bi iro ni mo mpa, bi otito ni mo uso.


*Cow & Gate*
*nỵeki awọn*
*ọmọde*
*LAGBARA*



Bi o ba fe ki ara omo re da-sasa gegebi ti omokunrin ti ara re da-sasa yi, o ni lati fun un ni COW & GATE—wara "RIRO" ti ko ni jeki inu re daru. Inu awon omode a ma a dun, nwon a si ma a ni itelorun bi nwon ba ngmu COW & GATE nitoripe o "RO" gegebi omi oyan.

Bi omo-owo ba ti dagba to omo osu meta tabi merin, o nilati ma a mu COW & GATE CEREAL onje ti o le die, o je nkan iyebiye fun awon omode lati iwon osu die titi de omo odun marun.




Ri i daju pe o bere fun COW & GATE—wara "RIRO"

**COW & GATE MILK FOOD**
*"The FOOD of ROYAL BABIES"*

# GBANGBA NI ASA NTA

## —SHOMOLU

**Adajo agba Ogbeni Olufide Shomola kilo fun awon amoxa ti o wa ni kotu giga Ibadan ni ogbon ojo osu kerin odun yi pe, on ko fekitenikeni ninu won maa wa ba on ni kolo inu iyara kotu fun oro bonkele kankan mo**

Adajo agba na se ikilo ki o to sun ejo gbigbo ti African Press Company ti ise olutewe Iwe Irohin Tribune siwaju si ojo keta osu karun odun yi.

Bi adajo agba na ti njade bo lati iyewu kotu lati wa bere ise oojo re, pekoreki ni o pade loya awon ajejo lenu ona abawo iyewu kotu na, eyi ni o mu ki o se ikilo bayi pe, "oko fe ki loya kan ninu iyewu lati wa ri mi, ayafi ejo olokolaya ti mo ngbo ni iyewu kotu, nitoripe nipa sise bayi, awon enia yio maa se abaki-abamo nipa ejo ti o wa niwaju mi ti nkoi ti da.

# Egbe Olope 'ngberu si

**Asaju egbe Afenifere ni Ipinle Ariwa Naijiria Malam Yusuf A. Bylam ti o ropo Alhaji Ibrahim Imam so pe egbe Afenifere tubo ngbile sii, o si npa sii ni agbara ni Ipinle Ariwa ju ti atehinwa lo.**

Asaju egbe Afenifere na so ey ni ile re Munchia Dan Aota ni Zaria lehin irin ajo re yi ka gbogbo Ipinle na.

Siwaju sii, Malam Bylam so pe, "Egbe Afenifere ri aye fi ese mule dada lehin ti awon adamodi osefu lasan ti fi egbe na sile.

O si kesi gbogbo awon enia Ipinle Ariwa lati gbaruku ti egbe Afenifere lese ki ipade ipare egbe olomi ati gbogbo iwa anikan ja po to nwon nhu le dopin.

# IGBESI AIYE UPP DORIKODO

Ibanuje dori egbe UPP kodo nigbati awon gbo pe awon asoju omo egbe won meji ti o wa ni Ile Igbimo Asofin Apapo fi egbe na sile wo egbe Alakuko ni ojo Aje ti ise ojo kokandilogbon osu kirin odun yi.

Oloye D.N. Abii ati Ogbeni Adeniran Ogunsanya ti ise ogbonkangi egbe Alakuko ni nwon se amona fun awon omo egbe UPP ti o sese jabo na de ori aga, nwon si joko pere larin awon omo egbe Alakuko ni Ile Igbimo Asofin.

Oruko awon mejeji na ni Ogbeni Bassey wu a Ukpong ati Ogbeni Samson udo Idiong asoju Ikot-Ekpene ati Ikot Ekpene Ariwa-Illa Orun.

Bi awon omo egbe Alakuko ti nyoruba won to, bena awon egbe UPP kari bonu bi akika ti nwon si npose sunrunsun.

*POLOWO*

OJA RE

SINU IWE

*IROHIN YORUBA*

## *BARIKA DE SALLAH*



Aworan oke yi ni ti ti okunrin kan ti o gbe agbo ri... Gege bi ise awon imale ni ododun ni awon ti nwon ba ti wo 'Ileya' ma npa ogba fun ajoyo odun na.

Ikode ti o de si eti gbo gbogbo enia lati Mekka wa ni pe, ni ojo eti ti ise ojo keta osu yi ni awon Alhaji odun yi yio goke Arafat, siwaju sii, irohin na tun so bayi pe awon ti o ti ongon mererin aiye wa lati wa gun oke Adfafat je 169,000 enia. Awon buburu tabi ighona ko si kolu enikeni ninu won.

Tri di isisiyi segesege ni odun Ileya mbo si ni Nigeria, ni Arowa ati awon ilu die ni Ipinle Iwo Orun Nigeria, ojo abamita ti ise ojo kerin osu karun odun yi ni nwon kirun odun Ileya. Sugbon Ojo Eti ti ise ojo kei osu karun odun yi ni awon musulumi Eko ati awon ilu miran kirun Odun Ileya.


# NOW–ROLLS-ROYCE 707s ON THE LONDON RUN




*Eto irinajo ayarabiasa ti ojojumo*

NISISIYI oko ofurufu titun ti a npe ni Rolls-Royce 707 ti wa fun awon onirin ajo ti o nlo si Londonu ati awon ile Oyinbo. Rolls Royce ti a mo jakejado aiye fun ero ti o dara julo li o se ero ti o ngbe oko ofurufu yi fo bi eiye Fun igbadun ati ifura nigbati o ba nrin irin ajo ninu oko ofurufu ayara bi asa, kesi Travel Agent re tabi ki o bere ni Nigeria Airways Booking Office ti o wa ni Broad Street, P O Box 136, Lagos (Telephone 24811) tabi ni Bank Road, P O Box 11, Kano (Telephone 3891) tabi awon ile ise oko ofurufu ni agbegbe re

## NIGERIA AIRWAYS

NIGERIA'S NATIONAL AIRLINE


Published by the Eastern Post Limited Elephant House, 214 Broad Street, Lagos and printed for them by the Olugbadewa Press 21 Ajele Street, Lagos
Ag. Editor (Adele Olotu) E. O. OLOFIN. N/2 439 Shittu Street, Ibadan.